# AJINDE ATI IGOKE RE -ỌRUN KRISTI

**Marku 15:42-47; 16:1-20; Iṣe Awọn Apọsteli 1:1-11.**

**ẸKỌ 435 -- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Nitori iwọ ki yio fi ọkàn mi silẹ ni ipò-okú; bẹ̃ni iwọ ki yio jẹ ki Ẹni Mimọ́ rẹ ki o ri idibajẹ" (Orin Dafidi 16:10).**

## l. Isinku Jesu

1. Josẹfu ara Arimatea ni o gbé oku Jesu, Marku 15:42-45.
2. A tẹ́ Jesu sinu iboji titun Marku 15:46.

## ll. Ajinde Jesu

1. Lẹyin ti Ọjọ Isimi ti kọja, awọn obinrin wá lati fi ororo kun oku Jesu, Marku 15:47; 16:1, 2.
2. Awọn obinrin naa ri ọdọmọkunrin kan ti o joko ninu iboji naa ti a ṣi silẹ, Marku 16:3-5; Luku 24:3; Johannu 20:11,12.
3. Angẹli naa sọ ọrọ itunu ti ajinde Jesu fun wọn, Marku 16:6-8; 14:28; Matteu 26:32.
4. Jesu fi ara han Maria Magdalene, lẹyin naa awọn ọmọ-ẹyin meji, ati lẹyin eyi O fi ara han awọn miiran bi wọn ti n jẹun, Marku 16:9-14; l Kọrinti 15:5.

## lll. Aṣẹ ti Kristi fun Awọn Ọmọ-Ẹyin Rẹ̀

1. Jesu fi aṣẹ ti o kari ayé fun gbogbo awọn ti o n tọ̀ Ọ lẹyin, Marku 16:15, 16; Matteu 28:19; Johannu 15:16; 12:48.
2. Awọn ami yoo maa tẹle iwaasu Ihinrere, Marku 16:17, 18; Luku 10:17, 19; Iṣe Awọn Apọsteli 2:4.
3. Jesu fi ara Rẹ̀ hàn laaye fun ogoji ọjọ, nipa ọ̀pọlọpọ ẹri ti ó daju, Iṣe Awọn Apọsteli 1:1-3.

## 1V. Ileri Baba

1. Jesu paṣẹ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe ki wọn duro de Olutunu, Iṣe Awọn aposteli 1:4, 5; Joẹli 2:28; Luku 24:49; Johannu 14:16.
2. Awọn ọmọ-ẹyin ṣi n fi oju sọna fun igbekalẹ ijọba kan ninu ayé. Iṣe Awọn Aposteli 1:6; Isaiah 1:26.
3. Jesu sọ fun wọn pe Baba ti dá awọn nnkankan duro nipa agbara Oun tikara Rẹ̀, Iṣe Awọn Apọsteli 1:7.
4. Ẹmi Mimọ yoo bà le wọn, wọn yoo si jẹ́ ẹlẹri fun Ọlọrun, Iṣe Awọn Apọsteli 1:8; 2:1-4.

## V. Igoke-Re-Ọrun Jesu

1. A gba Jesu si Ọrun, kuro ni oju wọn, Iṣe Awọn Apọsteli 1:9; Luku 24:51.
2. Awọn ọkunrin meji alaṣọ ala fi ọkàn wọn balẹ nipa ipadabọ Rẹ̀, Iṣe Awọn Apọsteli 1:10, 11; Marku 16:19; Danieli 7:13; Matteu 24:30; l Tẹssalonika 4:16; Ifihan 1:7.
3. Awọn ọmọ-ẹyin jade lọ, wọn n waasu nibi gbogbo, Oluwa si n fi idi ọrọ naa kalẹ nipa awọn ami ti n tẹle e, Marku 16:20.

## ALAYE

A ni akọsile nipa isinku, ajinde, ati igoke-re-ọrun Jesu ninu ẹkọ yii. Ni akoko ti a mu Un ati ni akoko ẹjọ Rẹ, awọn ọmọ-ẹyin kọ̀ Ọ silẹ wọn sá. Josẹfu ara Arimatea, ọlọrọ kan, ẹni ti i ṣe igbimọ pẹlu, tẹle Jesu ni ikọkọ nitori ibẹru awọn Ju. Ṣugbọn lẹyin ti a kan Jesu mọ́ agbelebu, a ri i pe Josẹfu fi igboya lọ siwaju Pilatu, o si bẹbẹ fun oku Jesu. Ohun ti o dabi ẹni pe o fi ibẹru si aya awọn ẹlomiran ni o fi igboya si aya awọn miiran.

O jẹ aṣa ni igba naa lati maa fi ikunra oloorun didun kun oku ki a to sin in. Nitori ko si akoko to, Ọjọ-Isinmi ti wọle tán, pẹlu ikanju ni wọn fi sin Jesu ni ireti pe awọn yoo wá fi ororo kun ara Rẹ lẹyin ti Ọjọ-Isinmi bá kọja tán. Ni kutukutu owurọ, awọn obinrin kan wá si iboji pẹlu ikunra oloorun didun ni ọwọ́ wọn. Bi o ti sọ lera-lera fun wọn pe Oun yoo ji dide, sibẹ o dabi ẹni pe wọn kò gbá otitọ naa mú. Ẹnu yà wọn, ẹru bà wọn, wọn si daamu nigba ti wọn ri i pe a ti yi okuta kuro lẹnu iboji naa, ti angẹli kan si sọ fun wọn pe, "Ẹ má bẹ̀ru: ẹnyin nwá Jesu ti Nasareti, ti a kàn mọ agbelebu: o jinde; kò si nihinyi: ẹ wò ibi ti wọn gbé tẹ́ ẹ si."

Iboji, pẹlu okuta ti o di ẹnu-ọna rẹ ko le dá Ọmọ Ọlọrun duro. Oun ni Ajinde ati Iye! Nigba ti akoko naa dé ti Oun ni lati dide, ko si ohun ti le da A duro. Awọn ọmọ-ogun Romu ṣubu lulẹ bi oku. Edidi ọba ko le dá agbara Ọlọrun duro. Jesu jade wá pẹlu iṣẹgun lori ikú, ọrun-apaadi ati iboji.

Awọn ọmọ ogun sare lọ si ilu nigba ti oju wọn dá kuro ninu owusuwusu ti o bò wọn nipa iṣẹlẹ nla ti o ṣẹlẹ, wọn si sọ fun awọn olori alufaa nipa ohun ti o ṣẹlẹ. Awọn alaiwa-bi-Ọlọrun wọnyii paṣẹ fun awọn ọmọ-ogun naa lati purọ, wọn si fi ọkàn wọn balẹ pe awọn yoo daabo bo wọn bi o ba di pe awọn ologun yoo fi ẹsun kan wọn pe wọn sùn ni ẹnu iṣẹ́. Ṣugbọn otitọ Ajinde Rẹ̀ di mimọ̀ fun ọpọlọpọ eniyan ni igba naa bi o tilẹ jẹ pe iroyin ti o duro lori iró ti awọn ọmọ-ogun pa ti tàn kaakiri.

### Ajinde Jesu Jẹ́ Otitọ ti O fi Ẹsẹ Mulẹ

Otitọ ti o fi ẹsẹ mulẹ ni o jẹ ninu itan akọsilẹ pe Jesu jinde kuro ninu iboji. Ajinde ni igbagbọ ati ireti Onigbagbọ. Koko ti iwaasu Paulu duro le lori ni Ajinde. Nitori ireti ajinde awọn oku ni a ṣe pe Paulu wá siwaju igbimọ. Awọn kan si wà ni ijọ Kọrinti pẹlu ti n sọ pe ajinde oku ko si. Paulu si kọ iwe ti a ko le gbagbe ni 1 Kọrinti 15, eyi ti o si ti jẹ idakọro ati ireti awọn Onigbagbọ lati igba naa wa titi di oni. "Ṣugbọn bi ajinde okú kò si, njẹ Kristi kò jinde….Bi a kò ba si ji Kristi dide, asan ni igbagbọ́ nyin, ẹnyin wà ninu ẹ̀ṣẹ nyin sibẹ" (1 Kọrinti 15: 13,17).

Jesu fi ara Rẹ hàn gẹgẹ bi eniyan fun pupọ awọn eniyan mimọ́ lẹyin ajinde Re. Nigba miiran O fi ara han ẹni kan ṣoṣo, nigba miiran fun awọn meji tabi ju bẹẹ lọ, ati nigba miiran O fi ara han ẹẹdẹgbẹta eniyan ti o pejọ pọ̀. Nigba kan laaarin awọn ifarahan Rẹ wọnyii ni O fun wọn ni aṣẹ yii pe: "Ẹ lọ si gbogbo aiye, ki ẹ si ma wasu ihinrere fun gbogbo ẹda. Ẹniti o ba gbagbọ́, ti a ba si baptisi rẹ̀ yio là; ṣugbọn ẹniti kò ba gbagbọ́ yio jẹbi." Gbogbo ẹda -- ọlọrọ, talaka, ẹni giga, mẹkunnu, ọmọwe ati alaimọwe – gbogbo wọn ni o gbọdọ gbọ́ nipa iwaasu Ihinrere bakan naa. Ki i ṣe aṣayan diẹ ti Oluwa ti yàn, ni yoo ni igbala ti awọn kan yoo si jẹ ẹni ikọsilẹ. Ipè fun "Ẹnikẹni ti o ba fẹ" gbọdọ dún jade, ẹnikẹni ti o ba si gbagbọ́ ni a o gbala. Ẹni ti ko ba si gbagbọ ni a o dá lẹbi.

### Agbara fun Sisin

Ki Jesu to gun oke re Ọrun, O sọ fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe ki wọn duro ni ilu Jerusalẹmu titi a o fi fi agbara wọ̀ wọ́n lati oke wá. Ifi-agbara-wọni yii yoo fun wọn ni aṣẹ fun iṣẹ-iranṣẹ wọn ati agbara lori gbogbo ipá ọtá. Eyi yoo fun wọn ni idaniloju pe awọn ami yoo maa tẹle iwaasu wọn. Wọn ni lati fi ède titun sọrọ, eyi ti ó ṣẹlẹ si wọn nigba ti a fi Ẹmi Mimọ́ wọ̀ wọ́n ni Ọjọ Pẹntikọsti. Jesu sọ pe: "Nwọn o si ma gbé ejò lọwọ; bi wọn ba si mu ohunkohun ti o li oró, ki yio pa wọn lara rara." Oluwa ko sọ fun wọn nibikibi pe ki wọn fi titobi agbara wọn hàn. A fi agbara fun wọn lati gbé Ọlọrun ga ati lati bukun awọn ọmọ eniyan. Wọn ko gbọdọ mọọmọ jade si gbangba ki wọn si tikara wọn gbé ejò lọwọ lati fi agbara ninu Ọlọrun hàn, ni ireti pe agbara Ọlọrun yoo gbà wọn, gẹgẹ bi aṣa awọn miiran lode oni. Itumọ ohun ti Oluwa wi nipa ọrọ yii hàn gbangba ninu Iwe Mimọ́. Ni akoko kan nigba ti igbesi-ayé Paulu ti n lọ si opin, o n ṣa igi jọ lati fi dá iná, ejo paramọlẹ kan si di mọ ọn ni ọrun ọwọ́. Awọn alaigbede ti o wà ni erekusu naa ri ohun ti o ṣẹlẹ, wọn n reti pe Paulu yoo ṣubu lulẹ yoo si kú. Wọn mọ bi oro ejo oloro naa ti buru tó. Ṣugbọn nigba ti Paulu gbọn ejo naa sinu ina, lai ni ifarapa rara, eyi fi agbara ti ó wà ninu Ihinrere hàn wọn (Iṣe Awọn Aposteli 28:1-6). Oluwa yoo pa awọn ti Rẹ̀ mọ́ lọwọ ejo ati ohun oloro bi a ba ṣeeṣi ṣe alabapade iru nnkan bẹẹ, ṣugbọn a ko gbọdọ fi ọkàn igberaga jade si gbangba lati fi han ayé, fun ogo ti ara wa pe a ni irú agbara bẹẹ.

## Igoke-Re-Ọrun Jesu

Fun ogoji ọjọ lẹyin ajinde Rẹ̀ ni Jesu ti fi ara hàn fun ọmọ-ẹyin Rẹ, nigba miiran ninu iyara ti a ti sé ilẹkun rẹ̀, nigba miiran ni eti okun. Nitori O wà ninu ara ologo O le fi ara hàn lojiji laaarin wọn, bẹẹ gẹgẹ ni O le nù mọ́ wọn loju lojiji. Ọrọ Ọlọrun sọ fun wa pe nipa ẹri pupọ ti o daju O fi ara Rẹ hàn laaye lẹyin ijiya Rẹ̀. O kọ́ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ni ọpọlọpọ ẹkọ nipa Ijọba Ọlọrun. O dabi ẹni pe oye yé wọn ju ti atẹyinwa lọ lẹyin ajinde Rẹ̀, nitori ọpọlọpọ ẹkọ ti Jesu ti kọ́ wọn tẹlẹ ri ni O fi hàn fun wọn gbangba ni akoko yii.

Ni ọjọ kan, bi O ti bá wọn pejọ pọ̀ ni Jerusalẹmu, O mú wọn jade lọ titi de Bẹtani ni Oke Olifi. Nibẹ ni O gbé fun wọn ni aṣẹ Rẹ̀ ikẹyin. Wọn ko gbọdọ tuka "kuro ni Jerusalẹmu, ṣugbọn ki nwọn ki o duro de ileri Baba, eyiti, o wipe, ẹnyin ti gbọ́ li ẹnu mi." Lẹyin naa O gbé ọwọ́ Rẹ̀ soke Ọrun O si sure idagbere Rẹ̀ fun wọn. Nigba ti O n sure fun wọn, a gbà A kuro lọwọ wọn, a si gbé E lọ si Ọrun. Wọn fi oju wọn ri I titi awọsanma fi gbà A kuro ni oju wọn. Bi wọn si ti n wo oju ọrun, awọn angẹli meji duro leti ọdọ wọn, wọn si wi pe: "Ẹnyin ará Galili, ẽṣe ti ẹ fi duro ti ẹ nwò oju ọrun? Jesu na yi, ti a gbà soke ọrun kuro lọwọ nyin, yio pada bẽ gẹgẹ bi ẹ ti ri i ti o n lọ si ọrun." Wọn pada si Jerusalẹmu pẹlu ayọ nla nla. Wo iru iyatọ ti yoo wà ninu ọkàn wọn nisisiyii pẹlu iru ibanujẹ ti o gba ọkàn wọn kan ni oru ọjọ ti a sin Jesu sinu iboji titun ti Josẹfu!

## Ipadabọ Jesu Kristi

O n pada bọ̀ lẹẹkeji! Awọn ọrọ wọnyii ti mú ayọ̀ bá ọkàn awọn eniyan mimọ́ Ọlọrun lati ọjọ pipẹ titi di isisiyii. A gbagbọ́ pe bibọ Rẹ̀ sun mọ tosi. Eyi ni ireti ologo ti ijọ, igba gbogbo ni a si n fi eti silẹ fun iro ipe ati ariwo olori angẹli.

Wo iru ọna iyanu ti Ọlọrun yàn fun ayanfẹ Ọmọ Rẹ̀ ninu ayé nihin! Ìbí irẹlẹ ati iku itiju, ṣugbọn ajinde ologo! Awọn ohun pataki ni o ṣẹlẹ laaarin igba kukuru yii. A ti fi Ọmọ Ọlọrun hàn, a ti kàn An mọ́ agbelebu, a ti tẹ Ẹ si iboji; lẹyin eyi, ni owurọ ọjọ kẹta, O ji dide! Isẹlẹ ṣẹ̀, awọn apata faya, awọn iboji ṣi silẹ, angẹli sọkalẹ o si yi okuta naa kuro. Kristi, Ọmọ Ọlọrun, fi ẹmi Rẹ lelẹ ki O ba le tun gba a pada.

Lẹyin ajinde Rẹ, obinrin kan ni o kọkọ fi ara Rẹ̀ hàn fún. Obinrin ni ẹni kin-in-ni ti o lọ sinu ẹ̀ṣẹ, obinrin si ni ẹni kin-in-ni ti o kọ́ de iboji ti o si kọkọ ri Olugbala ti O jinde. Obinrin ni ẹni kin-in-ni ti a kọkọ fi iṣẹ Ihinrere lé lọwọ: "Lọ……..wi." O sare lati royin ihin ayọ pe Jesu, Ọmọ Ọlọrun, ti bori agbara iku ati pe O wà laaye nisisiyii -- laaye titi lae!

Nitori Oun yè awa naa yoo si yè pẹlu. Ihinrere ologo! Ta ni le kọ ọ silẹ? O kú nitori awọn ẹ̀ṣẹ wa; O jinde fun idalare wa. O gun oke re Ọrun; O n pada bọ̀ wá lẹẹkeji. Paulu ka ohun gbogbo si ofo ki o ba le jere Kristi ati ki o si mọ Ọn ati agbara ajinde Rẹ. Njẹ awa n ka ohun gbogbo si ofo ki a ba le ni ipin ninu ipalarada? A ha n ja gidigidi ni tootọ ki a le wà ni imurasilẹ nigba ti Jesu ba de? "Olubukun ati mimọ́ ni ẹniti o ni ipa ninu ajinde ekini na" (Ifihan 20:6).

### AWỌN IBEERE

1. Ta ni sin Kristi sinu iboji titun ti oun tikara rẹ̀?
2. Ta ni Kristi kọkọ fi ara hàn lẹyin ajinde Rẹ̀?
3. Ta ni yí okuta kuro ni ẹnu iboji?
4. Ki ni aṣẹ ti Kristi fi fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀?
5. Awọn wo ni a oo gbala? Awọn wo ni a oo dá lẹbi?
6. Darukọ diẹ ninu awọn ibi ti a ti ri Kristi lẹyin ajinde Rẹ̀?
7. Nibo ni O ti goke re Ọrun?
8. Ikede wo ni awọn angẹli naa ṣe nigba ti Jesu goke re Ọrun?
9. Ikede naa ha mú ayọ tabi ibanujẹ bá awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀?
10. Ki ni aṣẹ ikẹyin ti Jesu pa fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀?